# OFIN ATỌWỌDỌWỌ ENIYAN TABI OFIN ỌLỌRUN
## Matteu 5:1-20
### ẸKỌ 95 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Awa kò gbọdọ má gbọ́ ti Ọlọrun jù ti enia lọ" (Iṣe Awọn Aposteli 5:29).**

## ALAYE

### Ariwisi

Awọn Farisi ati akọwe kan tọ Jesu lọ nitori awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ko gbọran si ofin atọwọdọwọ awọn alagba. Awọn Farisi jẹ awọn ẹlẹsin kan ti n jọsin pẹlu afẹfẹyẹyẹ pupọ, wọn si n ba awọn ọmọ-ẹyin Jesu wí nitori wọn ko ṣe bakan naa.

Idahun Jesu fun wọn jẹ ibeere nipa iwa ti wọn gan an. O rọrun fun awọn ẹlomiran lati rí wí sí ẹlomiran nigba ti awọn tikara wọn kò ṣe ohun ti o tọ́. ""Etiṣe ti iwọ si nwò ẹrún igi ti mbẹ li oju arakunrin rẹ, ṣugbọn iwọ kò kiyesi iti igi ti mbẹ li oju ara rẹ?" (Ka Matteu 7:3-5). Ni akoko miiran (Johannu 8:3-11), awọn akọwe ati awọn Farisi mu obinrin kan ti a mu ninu ẹṣẹ wá sọdọ Jesu. Wọn wi pe gẹgẹ bi Ofin Mose, a ni lati sọ obinrin naa ni okuta. Jesu wi fun wọn pe, "Ẹniti o ba ṣe ailẹṣẹ ninu nyin, jẹ ki o kọ́ sọ okuta lù u." Ọrọ wọnni da wọn lẹbi nitori ẹ̀ṣẹ ti o wà ninu igbesi-ayé wọn, wọn si lọ. Jesu dariji obinrin naa O si wi fun un pe ki o ma ṣe dẹṣẹ mọ́. Inu Ọlọrun ki o dun si ẹni ti o ba n ri wi si ẹlomiran ti o si n fẹ ki a jẹ wọn niya, nigba ti olufisun funra rẹ paapaa ni ẹ̀ṣẹ ninu igbesi-ayé rẹ̀.

### Ofin Atọwọdọwọ Awọn Alagba

Awọn Ju sọ pe awọn ofin atọwọdọwọ wọn jẹ ọrọ ti Ọlọrun ti sọ lori Oke Sinai – ofin afẹnusọ Ọlọrun, yatọ si ofin akọsilẹ ti Ọlọrun fi fun Mose (Ẹksodu 31:18). A ko kọ ofin atọwọdọwọ wọnyii silẹ ṣugbọn awọn ọmọ gbọ ọ lati ẹnu awọn baba wọn, wọn si fi i fun awọn ọmọ ti wọn, lati irandiran. Akoko wà ti a pa a da diẹdiẹ ki o le tẹ́ ẹni ti n sọ ọ lọrun, lai pẹ itumọ rẹ̀ si yipada. Bayii ni a ṣe pa Ofin Ọlọrun dà, ti ijọsin si di ibajẹ.

Awọn Farisi ni itara pupọ lati gbọran si àṣà ati ofin atọwọdọwọ eniyan ṣugbọn wọn kò ka ofin Ọlọrun si. Wọn rò pe awọn n ri ibukun ti ẹmi gbà nipa wiwẹ ọwọ ni ọna kan ati ni akoko kan (Marku 7:3). Wọn kò bikita nipa imọtoto bi ko ṣe nipa eto ọwọ wiwẹ.

### Ọkan Mimọ́

O gba ju fifi omi wẹ̀ lati wẹ eniyan mọ́ kuro ninu ẹṣẹ ati lati sọ ọ di mimọ́ niwaju Ọlọrun. Ninu Jeremiah 2:22 a ka pe: "Nitori iwọ iba wẹ ara rẹ ni ẽru, ki o si mu aró-ẹ̀ba pupọ, ẽri ni ẹ̀ṣẹ rẹ niwaju mi sibẹsibẹ, li Oluwa ỌLỌRUN wi."

**"Ki lo le w'ẹṣẹ mi nù?**
**Ko si lẹyin ẹjẹ Jesu**
**Ki lo tun le wo mi sàn?**
**Kò si lẹyin ẹjẹ Jesu."**

Ninu Orin Dafidi 24:3, 4, a ri awọn ohun ti o le mú eniyan yẹ lati bá Oluwa duro ni ibi mimọ Rẹ̀ -- "Ẹniti o li ọwọ mimọ́, ati aiya funfun." Nigba ti ẹni kan ba ronupiwada pẹlu irobinujẹ ẹni iwa-bi-Ọlọrun ti o si tọrọ idariji, Ẹjẹ Jesu a wẹ ẹ̀ṣẹ ati abawọn rẹ̀ kuro ninu ọkàn ati ayé rẹ̀. Iwa eniyan ni n fi han pe ọkàn ti di mimọ́. A maa n sọ pe ode ni ohun ti a ba ṣe ninu ti maa n fi ara han.

Ẹsin awọn Farisi jẹ ti ode ara nikan – ki i ṣe ti inu, nibi ti Bibeli kọ́ ni pe o ni lati wà. "Wẹ ọkàn rẹ kuro ninu buburu, ki a ba le gba ọ là" (Jeremiah 4:14).

### Otitọ Inu Nikan Ko To

Awọn akọwe ati awọn Farisi ṣe aapọn gidigidi ki igbesi-aye wọn le jẹ gẹgẹ bi ofin atọwọdọwọ awọn alagba. Ṣugbọn Ọrọ Ọlọrun kọ́ ni pe a ni lati sin Ọlọrun gẹgẹ bi ilana Rẹ̀. "Ọ̀na kan wà ti o dabi ẹnipe o dara loju enia, ṣugbọn opin rẹ̀ li ọ̀na ikú" (Owe 14:12). "Bi mo tilẹ nfọ oniruru ede tati ti angẹli, ti emi kò si ni ifẹ, emi dabi idẹ ti ndún, tabi bi kimbali olohùn goro. Bi mo si ni ẹbun isọtẹlẹ, ti mo si ni oye gbogbo ohun ijinlẹ ati gbogbo ìmọ; bi mo si ni gbogbo igbagbọ́, tobẹ̃ ti mo le ṣí awọn òke nla nipò, ti emi kò si ni ifẹ, emi kò jẹ nkan. Bi mo si nfi gbogbo ohun ini mi bọ́ awọn talaka, bi mo si fi ara mi funni lati sun, ti emi kò si ni ifẹ, kò li ere kan fun mi" (I Kọrinti 13:1-3). Awọn ẹbun wọnyii tobi, ṣugbọn o ṣe danindanin ju lọ fun eniyan lati ni ifẹ Ọlọkrun ninu ọkàn rẹ̀.

Ko si bi kankan ninu Ọrọ Ọlọrun ti Jesu ti yin awọn Farisi pe wọn n ṣe otitọ. Kaka bẹẹ, n ṣe ni o fi ẹṣẹ wọn ati aigbọran wọn hàn. Gẹgẹ bi apẹẹrẹ, Jesu darukọ ọna kan ti wọn kò fi pa ofin Rẹ̀ mọ́, "Bọ̀wọ fun baba on iya rẹ" (Ẹksodu 20:12) ni ofin karun-un, ṣugbọn awọn Farisi ti pa a dà. Wọn kọ́ ni, wọn si huwa bẹẹ pe ko ṣe danindanin fun

eniyan lati bọwọ fun awọn obi rẹ, tabi lati tọju wọn, bi oun ba fi iye owo kan tọrẹ fun ijọ. Ofin atọwọdọwọ wọn lodi si Ofin Ọlọrun lati le sọ ọ di asan (Marku 7:13). Bi wọn tilẹ yi Ofin Ọlọrun pada, sibẹ Ọlọrun yoo beere lọwọ wọn, wọn si wà labẹ idajọ nitori aigbọran wọn. "Oju ti o sin baba rẹ jẹ, ti o gàn ati gbọ́ ti iya rẹ, kanakáná ẹba odò ni yio yọ ọ jade, ọmọ idì a si mu u jẹ" (Owe 30:17). "Ṣugbọn bi ẹnikẹni kò bá pèse fun awọn tirẹ, papa fun awọn ará ile rẹ, o ti sẹ́ igbagbọ́, o buru ju alaigbagbọ́ lọ" (1 Timoteu 5:8).

**Awọn Ti N Fi Ete Jọsin**

Jesu pe awọn akọwe ati awọn Farisi ni "agabagebe" nitori wọn ki i ṣe olusin tootọ. Nipa wọn ni Isaiah sọ nigba ti o wi pe wọn n sin Ọlọrun pẹlu ete wọn ṣugbọn ki i ṣe pẹlu ọkàn wọn (Isaiah 29:13). Wọn ko sin Ọlọrun nitori wọn fẹ ṣe bẹẹ, ṣugbọn wọn fẹ ṣe afarawe ijọsin nitori wọn ni lati jọsin. Awọn eniyan kan wa lonii ti n lọ si ile-isin ti wọn si n ṣe afarawe ẹni ti n sin Ọlọrun ṣugbọn ki i ṣe ijọsin otitọ. Boya wọn n kọ orin, wọn tilẹ le kunlẹ bi ẹni pe wọn n gbadura, ṣugbọn ọkàn wọn kò sí ninu isin naa. Ijọsin asán ni. Ọlọrun kò kiyesi iru ijọsin bẹẹ, ijọsin wọn kò si mu ibukun kankan ba wọn. Ọlọrun a maa wo ọkan, ki i ṣe ode ara (1 Samueli 16:7). Bawo ni o ṣe n sin Ọlọrun? – lati ọkàn rẹ wá ni, tabi ni ete rẹ nikan ni?

**Ẹkọ Ti Eniyan**

Dipo Ọrọ Ọlọrun, wọn a maa kọ́ ni ni ẹkọ ti eniyan lode oni, nigba miiran gẹgẹ bi wọn ti n ṣe ni akoko awọn Farisi ati awọn akọwe. Eyi ni a n pè ni ẹkọ eke, nitori ki i ṣe gẹgẹ bi Bibeli ti wí. Jesu sọ nipa awọn olukọ ẹkọ eke nigba ti O wi pe ki i ṣe Baba ti n bẹ ni ọrun ni o gbìn wọn, a o si fà wọn tu. O ni wọn dabi afọju ti o n fẹ fi ọna han afọju, ati pe wọn o ṣubu sẹba ọna dipo ki wọn de Ọrun.

**Ọkàn Ti A Sọ Di Aimọ́**

Awọn ọmọ-ẹyin beere pe ki Jesu ṣe alaye ohun ti O n sọ ninu owe Rẹ nipa awọn afọju olukọ. Jesu n fi han wọn pe o ṣe danindanin lati ni ofin Ọlọrun ninu ọkàn ju ẹkọ awọn eniyan ni ode ara. Ẹṣẹ ninu ọkàn ni n fa ero buburu, olè, itanjẹ, igberaga, ati iwere (Marku 7:20-23).

Awọn ẹlẹsin kan a maa jẹ kiki irú awọn ounjẹ kan: ṣugbọn Jesu sọ pe ki i ṣe nnkan ti n bọ́ si ẹnu bi kò ṣe awọn nnkan ti eniyan n sọ ni o n fihan bi eniyan ba ni ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn rẹ.

**Yiyẹ Ọkàn Wò**

Ninu Jeremiah 17:9, a ka pe: "Ọkàn enia kún fun ẹ̀tan jù ohun gbogbo lọ, o si buru jayi." Yẹ ọkàn rẹ wò bi ẹṣẹkẹṣẹ tabi aigbọran ba wà nibẹ. Bi o ba bẹ Ọlọrun, Oun yoo fun ọ ni ọkàn titun, nipa ti ẹmi, Oun yoo si mú ọkàn ẹ̀ṣẹ ibẹ̀ kuro (Esekiẹli 36:26).

Dafidi, Onisaamu gbadura pe, "Ọlọrun, wadi mi, ki o si mọ̀ aiya mi: dán mi wò, ki o si mọ̀ iro-inu mi: ki o si wò bi ipa-ọ̀na buburu kan ba wà ninu mi, ki o si fi ẹsẹ mi le ọ̀na ainipẹkun" (Orin Dafidi 139:23, 24). "Jẹki ọ̀rọ ẹnu mi, ati iṣaro ọkàn mi, ki o ṣe itẹwọgba li oju rẹ, OLUWA agbara mi ati oludande mi" (Orin Dafidi 19:14).

Ki eniyan ba le gba awọn ibukun ati ere ti Ọlọrun ni fun awọn eniyan Rẹ, o ni lati gbọran si aṣẹ Ọlọrun, ki i ṣe ẹkọ eniyan. "Awa kò gbọdọ má gbọ́ ti Ọlọrun jù ti enia lọ" (Iṣe Awọn Aposteli 5:29).

**AWỌN IBEERE**

1. Ki i ṣe gbogbo ẹlẹsin ni Onigbagbọ́? Ki ni ṣe?
2. Ki ni eniyan gbọdọ ṣe ki o ba le di Onigbagbọ́ Bibeli?
3. Ki ni ẹ̀ṣẹ ninu ọkàn n mú wá?
4. Ki ni le wẹ ẹ̀ṣẹ naa nù?
5. Ki ni n sọ eniyan di alaimọ́?